ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 926 LAGOS SATURDAY JUNE 20— JUNE 26 1964 KỌBỌ MEJI (2D)

IRE WOLEDE !

# Awon Ara Meka Do-wolu Mosalasi Jimo Eko

EKO — Inu gbogbo awọn janmọ Mọsalasi Jimọ Eko ni ò dun nigbati nwọn gbọ irohin kan nibiti nwọn gbe ti nkirun janmọ lọsa ana wipe Ijọba ilu Mẹka fi ọkẹ meji (£40,000) ranṣẹ si awọn fun iranlọwọ Mọsalasi Jimọ tuntun ti awọn nfẹ kọ si Eko.



Alaji A.Y. Ojikutu, ọkan ninu awọn Igbimọ ti nṣe eto Mọsalasi Jimọ tuntun na.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, owurọ ijẹtani Ọlọla Sheikh Ali-Sugair, aṣoju (Ijọba Mẹka ti o wa ni Nigeria gbe iwe owo na tọ Ọlọla Tafawa Balewa, alakoso Ijọba Apapọṣe ilẹ yi ọ wipe gi o ba awọn gbe iwe-owo na fun awọnjanmọ Eko ti nwọn nfẹ tun Mọsalasi Jimọ na kọ.

A gbọ wipe ọkẹ mẹdọ-dọgbọn pọnun (£500,000 sarai ni awọn ara Eko nfẹ fun atikọ mọsalasi tuntun na, nitorina ọrọ lati ri awọn alanu larin awọn Larubawa awọn ni

(wo oju ewe kẹjọ fun iyoku)

ỌRỌ BẸHIN YỌ;

## Awon Osise Ko Ni Tete ri Owo Osu Won Gba Ninu Osu Yi

EKO - Irohin kan wa wa ni ilu Eko ni Ọjọ-ru ti nṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi wipe ifasẹhin diẹ yio wa fun awọn oṣiṣẹ jakejado ilu Eko ati ni ọpọlọpọ awọn ibiṣẹ Ijọba nitoripe iwe owo oṣu wọn fun oṣu yi, ko ni teto jalẹ, eleyi si ni abọ didaṣẹsilẹ fun ọjọ mẹtala ti awọn oṣiṣẹ ṣe ninu oṣu yi.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Awon Olopa Ni Oyinbo Kan Fe Doju Ijoba Nigeria Bole

## Awon Akeko Gba Loya Fun un

EKO— Oyinbo alawọ funfun kan ti orukọ rẹ njẹ Victor Leonard Allen. Olukọni ninu ile iwe giga kan ni ilu Oyinbo ni a gbọ pe awọn ọlọpa muwa siwaju adajọ kotu kan ni Eko lati dahun si ẹjọ ti nwọn mba ṣe lori ẹsun wipe o da ẹgbẹ gan ti o le da eto Ijọba ru silẹ ni ilu Nigeria.

Ọgbẹni Victor, onirungbọn yẹukẹ pẹlu oju kikoro bi ẹnipe o ti di arugbo ogoji ọdun sẹhin, ni awọn ọlọpa sọpe o da ẹgbẹ makaruru kan silẹ ni ilu Nigeria larin ogunjọ oṣu karun ati ọjọ kẹtadinlogun oṣu kẹfa ọdun yi eyiti o lodi si ẹsẹ kẹtalelọgọta ninu iwe ofin Ijọba ti o mu awọn ọdaran fun un iru ẹṣẹ bayi.

Adajọ ko ti gbọ ọrọ ẹnu ọdaran na, ṣugbọn o paṣẹ pe ki awọn awọn ọlọpa fisi itimọle titi di ọjọ kini oṣu keje ọdun yi.

Ọga agba awọn ọlọpa kan ti o nṣiṣẹ ni ọfisi awọn ọlọpa ọtẹlẹmuyẹu (Central CID) ọgbẹni Chales Kadu-ru to tun jẹ alatako fun Victor, sọfun adajọ kotu, Ọgbẹni A.R. Bakare wipe on lodi si pe ki nwọn gba iduro ọdaran na nitoripe irohin kan nsọfun awọn wipe diẹ ninu awọn aṣiwaju awọn oṣiṣẹ wa ninu ... apamọ-pamọ na, nipa ṣiṣe bayi, aye yio wa fun awọn ọlọpa lati ṣe iwadi ọrọ na siwaju.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa ọdaran na awọn ọlọpa tun fi ye wa pe Ọgbẹni Victor

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Alhaji Gbadamosi Pe Omo Ajao L'ejo

EKO—Ni ọjọ iṣẹgun ti nṣe ọjọ kerindin-logun oṣu yi ni Kotu giga ni ilu Eko gbọ ẹjọ ti Alhaji Sule Oyeṣọla Gbadamosi pe ọmọ oloogbe Oloye J. A. Ajao ti o nje Aderọgba fun ọrọ abuku kan ti ọmọ na sọ si on lori eyiti on fẹ gba ọkẹ meji din lẹghaarun pọun (£50 000) lọwọ wọn fun owo ipanilara ti ọrọ na mu ba on.



Ologbe Oloye J. A Ajao

Lẹhinna o tun mẹnu kan ẹjọ kan ti ọmọ ologbe Oloye J A Ajao pe on na fun ọrọ abuku lori eyiti o fẹ gba ọkẹ marun le lẹgbaarun pọun (£90,000) fun owo ti o sọ wipe on jẹ ni gbese lọdọ baba wọn ọrọ yi ni o sọ rigbati o ndahun si ibere kan ti agbẹjọro kan mbilcere.

Alhaji Gbadamosi sọpe ọgbẹni Aderọgba Ajao ọmọ oloogbe Oloye J A. Ajao sọrọ ABUKU kan si on laarin oṣu kẹjọ ati ikẹsan ọdun 1962 wipe "Owo ti Gbadamọsi ya ko le san baba on si jẹ okan ninu awọn ti o jẹ lowo sibẹ nan ko le saan," ati wipe iru ọrọ bayi ti ọmọ ologbe Oloye Ajao sọ jẹ ọrọ eke ati arankan.

Nigbati ọgbẹni agbẹjọro, Michael Ọdesanya fi ibeere kan siwaju Alhaji Gbadamosi lori bawo ni o ṣe gbọ ọrọ na o dahun pe ọpọ eni lo sọfun on wipe Ọgbẹni Aderọgba Ajao nsọrọ on laidara bi on ko ti lagbara lati san gbese ọkẹ marun din lẹgbaarun pọun (£90,000) kan ti on jẹ baba on ti o jalaisi.

O tun sọ pe on ko le se iranti gbogbo awọn ti nwọn sọrọ na fun on ṣugbọn on rii wipe ọgbẹni R A. Allison olo gbe oloye Samuel Ṣonibarẹ ati awọn miran wa lara awọn ti nwọn sọrọ na fun on, bẹẹni on ko si ranti ọjọ gangan ti nwọn sọrọ na fun on.

Ninu ibeere ti agbẹjọro fi pari ọrọ rẹ, o wadi lọwọ Alhaji Gbadamọsi boya otitọ tabi iro ni wipe ọgbẹni Aderọgba Ajao eniti o jẹ alabojuto ogun awọn ẹbi oloogbe Ajao pee lẹjọ fun ọkẹ marun din lẹgbaarun pọun (£90,000) o si dahun wipe "BẸẸNI".

# Iyawo Kan Büsekun Tori Ewon Osu Mesan

EKO-Lori ẹwọn oṣu fi adajọ kotu kan ni Eko ju Iyawo ile kan si ni o sọkun kikoro, eniti oruko rẹ nje Iyabọ Lawal, eni ọdun mejilelogun.

Adajọ kotu na, Ọgbẹni Emmanuel Oshodi sọpe on ri wipe Iyabọ jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan nitoripe o ngbidanwo lati ran rẹ, Latifu Lawal lọwọ ki o le ri aye sa sa jade kuro ninu ọgba ẹwọn ni ọjọ keje oṣu yi.

Ọrọ ti awọn ọlọpa sọ niwaju adajọ ni wipe, nijọjọ keje oṣu yi, Iyabọ lọsi ọgba ẹlẹwọn ni Ikoyi lati lọ be ọkọ rẹ wo ninu itimọle ati pe lẹhin ti nwọn ti jọ sọrọ tr nwọn si da gbere fun ara wọn tan, Iyabọ duro ni itosi ọna, o fa ẹru kekere kan yọ ni abiya rẹ, o si juu si ile ihamọ nibiti ọkọ rẹ gbe wa. Bi o ti ju ẹru kekere na sinu ile ihamọ ti ọkọ rẹ tan ni ọkan ninu awọn akọwe ọgba ẹlẹwọn ba ri i, nwọn si mu.

Nigbati nwọn tu ẹru kekere na, nwọn ba ọbẹ mẹta ninu rẹ, fun ọkọ rẹ lati fi ge waya alawon ile ẹlẹwọn ki o ba le ri aye salọ.

Iyabọ sọfun adajọ wipe irọ ni ọga awọn ẹlẹwọn pa mọ on, nitoripe on ko ju ẹru kaukan si ọkọ on.

## Iyawo Akoko Kan Ko Rown San

KABBA-Adajọ Kotu Ijọba ibilẹ Ogaminana kan ni ki awọn ọlọpa lọ ti ebinrin kan ti o nje Asiawu Abosuhai ti o ja iwe ikọsilẹ fun ọkọ rẹ ṣugbọn ko ri owo san mọle titi di igbati yio fi le san owo ori rẹ fun ọkọ rẹ na.

Gẹgẹbi nkan ti a gbọ nipa ẹjọ ti obirin na pe ọkọ rẹ, Usman Abakta ninu meji kotu awọn akọkọ, pọnun meji o din logoji ati sile mejila abọ ni gbogbo owo ti bale rẹ sọ wipe on san lori rẹ.

Nigbati nwọn re ẹjọ na titi, adajọ kotu ijọba ibilẹ na ni ki obinrin na lọ da pọnun mẹdọgbọn ati sile meji abọ pada fun ọkọ rẹ, nigbati o tu tobi awọtẹlẹ rẹ pọnun mẹta pere ni o ri da sile. Adajọ na si fun un ni ọsẹ kan wipe ki o tete wa owo yoku kan.

Nigbati ọsẹ kan pe, Asiawu ko ri owo ọkọ rẹ mu wa, eyi lo jẹki adajọ sọ wipe ki nwọn lọ ti i mọle titidi ọjọ ti yio fi ri owo san.

# Kole-Kole Kan Wewon Iwe Yiyi

EKO—Ọkunrin kan, eni ọdun mẹtalelọgbọn ti orukọ rẹ nje Benedict ọlajide Akinọla ti o si tun nje orisi orukọ mejin lẹọkansoṣo pẹlu fifi igba mẹta jura tẹlẹri ninu ọgba ẹwọn ni adajọ kotu kan ni Eko sọ si ẹwọn oṣu mejila ni ọjọ Iṣẹgun ti nṣe ọjọ kerindilogu oṣu yi nitoripe o yi iwe-owo banki pada si ọtale lodunrun pọun o din mẹdogun ni ọjọ kẹtala oṣu keji ọdun yi.

Awọn ọlọpa si nwọn mba rojọ sọfun adajọ wipe Akinọla mu iwe owo (cheque) na lọsi banki ni ọjọ kẹtala osu keji ọdun yi lati lọ fi gbowo o ṣee bi ẹnipe awọn oyinbo ile onisowo moto kan (Mandilas and Karaberis Limited) ni Eko ni nwọn fifun lati fi gbowo.

Ọbinrin kan ti orukọ rẹ nje Rosaline Bonvie, akọwe owo (Cashier) to aṣiṣe ni banki ti Benedict ti gbo wo jẹri niwaju adajọ wipe lẹhin igbati ọdaran na ti gba owo tan ni ọga awọn ti o jẹ oluṣiro owo (Accountant) ri aṣiṣe ninu iwe owo na o si paṣẹ pe nwọn maṣe jẹki Akinọla ṣise nikẹhin ni awọn ọlọpa ba de nwọn si muulọ si kotu

# Ijoba Apapo Kuna Ninu Ejo Enahoro

**EKO-Lẹna lọọlọ yi ni a gbọ wipe ile ẹjọ giga ni Eko tu ẹjọ ti Ijọba Apapọṣe pe Oloye Ẹnahoro ka niau eyiti Ijọba fẹ gba ojilenirinwo pọnun fi din pọnun mẹrinla (£426) lọwọ rẹ, gẹgẹ i owo ti Ijọba na lori re fun mimu Oloye Ẹnahoro pada bọ wa si Naijiria lati jẹ ẹjọ idajọ ijọba apapọ bolẹ ni ọdun ti o kọja, owo yi si ni kotu kan ni London sọ pe ki Oloye Ẹnahoro san.**

Adajọ agba, Ọgbọni Charles Daddy Onyeama tu ẹjọ na ka nitori idi wipe idajọ ti kotu London ṣe yi ki i ṣe ti ibara eni ṣẹjọ ni, bi koṣe ti ọdaran, nipa bayi, Olone Ẹnahoro, ẹniti o dite lati doju ijọba apapọ bolẹ ti o ṣẹ nṣe ẹwọn ọdun mẹdogun lọwọ lori na, ko jẹbi rara.

Ọgbẹni Yaba Jinadu, ti o jẹ agbẹjọro fun Ijọba Apapọṣe sọfun adajọ agba pe ẹjọ mimu ọdaran wa fun idajọ ti ijọba apapọ pe Oloye Ẹnahoro jẹ ẹjọ ọdaran.

Agbẹjọro fun Ijọba Apapọ tun jiyan siwaju wipe bi o ba jẹ bẹ e ni, iru ẹjọ ti Ijọba ti kọkọ pe Oloye Ẹnahoro, ti o si wa ṣaju eleyi ninu ile ẹjọ ni London lori ẹsun ọtẹ si Ijọba Apapọ ko le ṣe ka kun ẹjọ ti ọdaran rara.

Ninu esi ti adajọ agba fi, o ni on iodi si ọrọ ti agbẹjọro sọ, nitoripe ni iwọn igba to ti jẹ ọdaran ni awọn pe Ẹnahoro, gbogbo iru ẹjọ kẹjọ yowu ti o ba wa lọna bẹ nilati jẹ ẹjọ ọdaran ati wipe on ko ri koko kan dimu ninu ọrọ ti agbẹjọro na ri sọ, idi eyi, on tu ẹjọ na ka.

Idi nkan ti Ijọba Apapọ fi fẹ lati gba owo na lọwọ Oloye ni wipe owo na jẹ eyiti kotu kan ni London paṣẹ ki Ẹnahoro san inawo ti Ijọba Apapọ ṣe lori Oloye Ẹnahoro.

Ọgbẹni Adesanya ti nṣe iṣẹ agbẹjọro latiọdun meje sẹhin, ṣugbọn lori ofin tuntun kan ti awọn ṣeṣe ṣe fun awọn lọya ninu ọdun ti o kọja yi ni nwọn fi yọ kuro ninu iṣẹ agbẹjọro titi igbesi aiyẹ rẹ.

Ni kete ti adajọ ti ṣe idajọ tan Ọgbẹni Adesanya ti o wọ aṣọ awọtẹlẹ dudu (Black Suit) ti a fun adajọ agba siwaju ọpọlọ ẹni ti nwọn pejọ sinu kotu a ti agbegba kotu o si wa ni isori. o fun ibannije titi o fi jade niuu ẹjọ ti ọjọ, isanwo rẹ ti o jẹ obirin oyinbo si tẹle lẹhin.

Ọjọ keji oṣu kẹ a ọdun yi ni Ọgbẹni Adesanya kuna nipa ẹjọ kotẹmilọrun ti o muwa si kotu giga ni Eko.

# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE ti o kun fun irohin aladun losose.




## Nwọn Gba Agbada Lọwọ Loya Kan

EKO — Ọgbẹni Ọlayinka Adesanya ti nṣe agbẹjọro ni ilu Eko ni a gbọ wipe adajọ agba, Ọgbẹni Adetokunbọ Ademọla yọ kuro ninu iṣẹ agbẹjọro ninu idajọ kan ti o ṣe ninu kotu nla ni Eko ni ọjọ Aje ti nṣe ọjọ kẹdogun ẹṣu yi, o si paṣẹ pe ki awọn ijọba fi ọrọ idajọ yi ransẹ si ile-ẹkọ awọn agbẹjọro (London Inns of Court) nibiti lọya agbẹjọro na ti gba oye agbẹjọro rẹ, nitoripe o hu iwa alaiṣododo.

Ohun ti o fa ọrọ yi ni pe Ọgbẹni Adesanya gbimọ pọ lati jale, lati yi iwe ati lati hu iwa irẹjẹ lori eyiti adajọ kan ni Ilu Calabar ni ki o lọ sẹwọn oṣu mẹrin t bi ki o san adajọ pọnun (£150) nitoripe o jẹbi ẹsun na.

# ELETI-OFE

(A NJU WON KO ŞE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kesoko Street, Lagos; "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 926 SATURDAY June 20 — June 26 1964


## ORO OLOTU

# Awon Osise Jagunmolu

Nitori oro ti Olotu wa ko ni ose ti o koja ni a gbe ti be gbogbo awon osise wa ti nwon da ise sile wipe ki nwon hu iwa omoluwabi ki nwon pada senu ise, ki nwon le ri aye ba awon alamojuto eto Ijoba jiroro lori oro ifikun owo osu won.

Inu awa onirohin Eleti Ofe dun lati ri wipe awon osise na hu iwa omoluwabi, nwon jagun, nwon molu, nwon si pada sinu ise won. A gba fun won lonakona.

A gbo wipe nkan ti o fa a ti Ijoba Apapose l'Eko fi fonmu lori ifikun owo awon osise ni ti owo goboyi ti nwon fe na lodun mefa lori awon nkan idagbasoke fun awon ara ilu yi.

E jeki a so otito fun ara wa: OWO WA NIBITI O GBE WA, nnkuna ti awon alunniso wa nna lojojumo ni ko jeki a mo wipe awa ara Nigeria lowo lowo rara.

Ni odo awon osise wa oro na ti di GBANGBA DEKUN KEDERE BE E WO. Gbogbo won gba ni nwon ti mo ajadi apere ti a gbe nda owo Ijoba wa si.

Bi a ko ba fe se oro awon osise wa yi ni awon IJO NRU ALUFA NSANRA, o yeki awon alunniso eto Ijoba wa wa ona lati din melo kan ku ninu awon Minisita wa; ise melo ni awon asoju wa nse ni ile igbimo asofin ti nwon fi ngba nkan bi egberun ponun lodun? Se ti agbada ti nwon nda kiri bi ti awon kan ti nwon npe ni ole ote le Alufa ni?

Eleyi ko to nkan ti a le fun won ni ile ofe gbe si ni Ikoyi pelu owo ijoko ojojumo ati owo irin ese ti Ijoba tun nsan fun enikokan won.

Bi a ko ba fe janyinjanyin ninu ile ngbalagba ni ekeji o ye ki awon alunniso Ijoba wa mo ona ti nwon yio gba lori awon akowe oga ise Ijoba ti nwon nfi ile gbigbe se iranu ni Ikoyi pelu awon obinrin oyinmu-ege ti awon osise ni nwon kojo sinu Banki ajoda ti nwon nsan ogojì-o le legberin ponun (£840) fun won fun owo pepa ti nwon nka pelu auke ti nwon nkun lodi leso

Bi a ba ti din inakuna wa ku, a ori wipe ko ni soro fun wa lati san owo fun awon osise wa ti nwon nwon ese ise losan loru lati mu ilu duro.

# Koforun Awon Minisita Kan Ijangbon Lowo Awon Osise

EKO — Ipade awon asoju Ijoba Apapo awon oga ise adase (Private employers) ati awon osise bere ni Eko ni ojo Isegun ti nse ojo kerindinlogun osu yi lati foju mu wo, ati jiroro lori abo iwadi nipa ekunwo awon osise eyiti Ogbeni Morgan ti gbe kale lati osu kewa odun to koja (1963).

Ni odo awon asoju fun awon osise awon enia medogun ni nwon wa si ipade na, awon bi i Alhaji H.P. Adebola, awon Ogbeni W.O. Goodluck, N.S.U Bassey, L.L. Borha E.N Okong ati E.O Achambar, Gogo Ezerebe, Olu Orisilade, J.M Okiredo Mallam A. Kaltungo (Lati Ipinle Arewa) ati H.W Ugwuala (Lati Ipinle Ila-Orun) ati J.O James (Lati Ipinle Iwo-Orun) sugbon awon asoju wonyi ko ti wa ni isepo tabi ori ipinnu kan lori asoju fun awon osise Ipinle Iwo Agbedemeji (Midwest)

Ni idi tabili ti Ijoba Apapose awon wonyi ni nwon se asoju. Oloye Okotie-Eboh, (Minisita nipa eto owo Ijoba Apapo) Ogbeni Jacob Obande (Minisita fun dida ile, ise sile) Oloye J.M. Johnson Minisita nipa fun eto Ise Alhaji Waziri Ibrahim (Minisita fun isunna owo ati idagbasoke ilu. Ogbeni R.A Njoku (Minisita fun eto irinnajo) Dokita K.O Mbadiwe (Minista fun eto oko ofurufu) ati Zannar Bukar Dipcharima (Minista fun owo sise).

Awon oga ile ni ilu Naijiria yan asoju mefa pere. Ni ibere oro alaga awon osise, Alhaji H.P Adebola o dahun wipe pelu okan kansoso ni awon ti awon je asoju awon osise fi wasi ipade yi lati le fi aye awon han fun gbogbo agbaiye ati pe o je didun inu awon lati yanju iduro awon lori awon alaye kan, o si tun dahun wipe awon ti wa lati huwa bi olore sugbon

wo iyoku leju ewe karun)


DAGENITE

BATTERIES

*give you a longer run for your money!*



# Oga Ile-Ise Kan Wo Ijangbon

EKO–Adajọ kotu kan ni Eko sun gbigbọ ẹjọ didimọpọ kti jiji ẹdẹgbẹrun pọnun, (£900) ninu eyili awọn ọlọpa mba ọga ile iṣẹ kan. Ọgbẹni Joseph Adeyemi ṣejọ, titi di ọjọ ọgbọn oṣu yi (June 30 ati nẹikeji rẹ ti orukọ rẹ njẹ Lasisi Ajayi, gbẹna-gbẹna.

Ninu ọrọ si awọn ọlọpa sọ ni iwaju adajọ, nwọn ni awọn ọdaran mejeji pamọpọ nwọn si fi eru gbowo lọwọ Gabriel Adebawo ninu oṣu keji ọdun yi nigbati o gbe iṣẹ agbaṣe (Contract) fun Adeyemi lati ṣe ni Surulere.

Gẹgẹbi ọna eru ti nwọn gba fi gbowo, awọn olọpa ni Adeyẹmi Ajayi lo si ile Adebawo, nibẹ ni Adeyemi fi Ajayi han gẹgẹbi onişowo ninu Simẹnti (Cement dealer) ati lati ọwọ ẹniti on ti ra imenti ti o to ẹdẹgbẹrin pọnun (£00) fun ag ase iṣẹ na, ṣugbọn ki nwọn to lọ, Adeyemi sọfun Ajayi pe ki o wọ agbada kan ki o si ṣe gẹgẹbi Ọgbẹni kan ti orukọ rẹ njẹ Fagbẹsan.

Laifaagun lọ titi edini apamọ pamọ awọn ọdaran na mu ẹ debawo, o si fun wọn ni ẹdẹgbẹrun pọnun, o si dahun wipe wọn ki nwọn ṣewe ẹri (Receipt) lati fi han pe awọn gbowo, ṣugbọn gbogbo igbati nwọn jọ nṣe aṣalọwọ ifura de si ọkan Adebawo o ba ranṣẹ pe pe ọlọpa.

Adeyẹmi sọfun Adebawo pe dipo ti on iba ra apo simenti kan ni ṣile mejila-abọ lati ọwọ awọn ijọba ti nkọle fun awọn oṣiṣẹ, on Adeyọmi yio ṣe eto pẹlu oniṣowo kan ti o le ta a fun ni ṣile mesan; nibẹ ni Adeyẹmi ba mu Adebawo iẹhin lọsi Suru-lere nibiti Ijọba gbe akọle fun awọn oṣiṣẹ.

# Koforun

**O bere loju ewe keri**

ko ni si fifaramọ lori pọun mẹrinle-logoje (£144) lọdun gẹgẹbi owo oṣu f u n Lebira; bẹẹn awọn si nfẹ ki Ijọba fọwọsi awọn ibere meje wọnyi:

Ekini ni lati pa owo ọya irin-ajo ti a w ọ n Minista ati awọn aṣoju Ile Igbimọ ngba rẹ patapata.

Ekeji ni lati pa o w o iyilọkan pada ti awọn ọga iṣẹ nlanla ngba rẹ.

Ẹkẹta ni lati dẹkun owo sisan fun ile ti awọn ọga nlanla wọnyi ngbe.

Ekẹrin ni lati pa ipo Igberiko rẹ nitoripe ipo na ko jamọ ohun kan to nilari bikosepe bi aṣoju tabi onigbowọ ẹ g b ẹ oṣelu ni nwọn jẹ.

Ẹkarun ni piparẹ owo ile ti Ijọba nsan fun awọn asoja wọn n'i n u ile igbimọ l o'r i Ile ti nwọn ngbe lẹhinna ni alhaji Adebọla w a f ọ

ṣangba mọlẹ nigbati o ṣe alaye rẹfẹ wipe eyi jẹ igba ti o tọ lọ lati bere fun iwadi lori bi ọpọlọpọ enia ati awọn ọga iṣẹ onipo nla ninu iṣẹ Ijọba ti ṣe di ọlọrọ nlanla, bi ọpọlọpọ miran ti nṣe si awọn oyinbo to fẹ do iṣẹ silẹ, ti awọn nsa pada si ilu wọn lori ẹsun wipe ewọn ọga nla-nla wọnyi a ma fẹ gba owo biribiri lọwọ awọn oyiubo wọnyi ki nwọn to le gba wọn laye lati da iṣẹ silẹ ni ilu wa, (Nigeria).

Ibere keje na ba ti didaduro lẹnu iṣẹ awọn iyawo, ati awọn ale koforun awọn Minisita ati awọn akọwe Minisita ti nwọn nṣiṣẹ ni banki gbogbo, fun wakati mẹfa pere loojọ ti nwọn si ngba owo ribiribi to ojile-lẹgbẹrin (£840) pọnun lọdun n owo oṣa.

Alhaji Adebọla fi nvẹ ipade na pe ogunlọgọ awọn ọmọdakunrin ti nwọn ko ri iṣẹ ṣe, bẹẹ ti nwọn jade ile ẹkọ giga wa, ti nwọn le iṣe iṣẹ ju awọn ati ale koforun wọnyi lọ, ti nwọn ma ule akoko ibiṣẹ danu lasan lori ọrọ awada ati ofofo ati kikun atike ati ete ati ipenpeju lẹnu iṣẹ.

Ni ipariọrọ rẹ, Alhaji Adebọla sọpe akoko to wayi lati fọ ilu wa mọ tanitoni kuro ninu eeri ẹgbin.

# Alase Kan Lo Sewon odun Mefa

IJẸBU — ODE Alase ati iranṣẹ k a n, Jeremaiah Ayanoke ti nṣe iṣẹ ase fun adajọ kotu giga kan ni Ijẹbu Ode, Ọgbẹni Charles Madarikan, ni adajọ kan ni kotu ibilẹ ni Ijẹbu Ode sọ sẹwọn ọdun mefa lori ẹsun wipe o ji ọga re ni adọjọ pọnun (£150), oruka wura kan, ikọrun obinrin pẹlu dogbodobgo n sale ti nwọn fi wura ṣe ati redio (Radio) kekere kan ninu lọọjọ yi.

Ninu ọrọ ti ọga alase na sọ fun adajọ, ti orukọ rẹ njẹ Oloye D O Oguntoye, o sọ wipe ọdaran na sa kuro ni ile isinmi ti Ijọba ilu Ijẹbu Ode (Government Rest House) ninu eyiti awọn ngbe ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu ti o kọja lẹhin ti on ti lọ si ibiṣẹ tan ko si ṣe onjẹ silẹ fun on rara, beni ko tilẹ fọ awo ti on fi jẹun lati owurọ tabi ki o tilẹ ko wọn kuro lori tabili onjẹ.

Nikẹhin ni on wa ri pe ọpọlọpọ ohun ini on ati owo paapa di afẹku, lori eyi ni on ba mu ọrọ siwaju awọn ọlọpa, ṣugbọn gẹgẹbi irohin ti awọn ọlọpa gbọ nipa ibiti ọdaran na salọ si, nwọn lọ sibẹ nwọn ba ri mu u ni ile ọti kan (Luxury Hotel) ni ilu Ibini ni Iwọ-Orun agbedemeji (Midwest), awọn ọlọpa si b a igo ọti meji lọwọ.

Şiwaju ẹsẹ ti ọdaran na sẹ ọga rẹ sọ pe on ti pinnu lati ṣe ẹkunwo owo oṣu rẹ ni ipari oṣu karun ọdun yi, nitoripe iṣẹ rẹ tẹ on lọrun.

bi awọn ọmọde ti ri Adeyẹmi ni nwọn bẹrẹsi kigbe wipe "Ọga, Ọga"

Agbẹjọro awọn ọdaran na Ọgbẹni Kẹhinde Sofọla sọfun adajọ kotu wipe ki o da awọn ẹjọ on silẹ nitoripe awọn ọlọpa ko ti fi ẹsun ole jija kan awọn elejọ on, nitoripe Ọgbẹni Adebawo lo nwa ọja ọpọ lati na ti o si gba lati san ẹdẹgbẹrun pọnun fun ọja ti o fẹra gẹgẹbi adehun.

# Oloye Kayode Kabo



Oloye FANI-KAYỌDE

A ki Oloye Fani-Kayọde ku abọ inu ajo to ṣe lọ si ilu Oyinbo laipẹ fun ọrọ ati da ile iṣẹ Aṣoju Ijọba Ipinle Iwọ Orun pọ mọ ti Ijọba Apapọ ti Nigeria.

Ẹ KU ABỌ

**Ka oro awon Olepabinrin to ba won D'awo loju ewe kefa iwe yi.**

# Awon Olopa Obirin W'awo Apapando Ni Ijebu Igbo

IJEBU — Adajo ile ejo Ijoba ibile kan ogbeni oloye Abiodun Oguntoye lenu lo olo yi, sun gbigbo ejo awon okunrin meji kan ti oruko won nje Ganiyu Salawu ati Oladipo Onjiribo siwaju lori esun sise imule-awo pelu awon olopa obirin meji ni Ijebu Igbo.

Gegebi oro ti awon olopa so niwaju adajo, nwon ni awon odaran meji na se ibura imule awo pelu awon obirin olopa meji ti oruko won nje Esther Discen ati Abigail oluwaja awipe on yio ta ayo a adamodi owo "Ijebu" ti nwon gbe ile won fun won ni edinwo, au o si kilo fun awon obirin olopa na lati fi awo na pamo.

Ninu eri Abigail niwaju adajo o ni on ati Esther parada gegebi obinrin onisowo ti nwon wa lati Ibadan nigbati awon de ile Salawu ati pe lehin ti awon ti so ohun ti awon ba wa tan gegebi awon ti nwon ora owo makaruru kiri Salawu dahun pe afi bi a on ba koko mule awo na ki awon to le ri owo makaruru na ra.

Abigail tun so wipe ki o to di wipe awon mule ori eni kan ni on ati Esther kunle le lori lehinna ti Salawu ba pa obi ati orogbo o tun pese eje ati oogun miran sile.

Lehin ti awon ti se aasa imule yi tan ni Salawu ba wo inu yara re lo o si mu adojo poun ( £150 ) owo agbelese na jade fun tita ni ogofa poun (£120

Nwon siguro ejo na lowo,

# Agbejoro Ijoba Tako Ejo Ikania

EKO — Oloye, Olu Omololu, agbejoro agba fun Ijoba Apapo ni ilu Eko, ni Ojo Ri, ti nse ojo kewa osu yi ninu kotu giga ni Eko ti se iwe atako kan lori oro kika enia ti Ijoba se ni odun to koja (1963) eyiti Ijoba Ipinle Ila-Orun (East tern Nigeria Goverment) fi mba Ijoba Apapo ni Eko se ejo nitoripe ikanja na ko pe, o si ti gbe siwaju adajo agba kan l'Eko fun gbigbo.

Ninu iwe atako na, Oloye Omololu ni on nfe ki kotu giga tu ejo na ka o si se alaye meta pataki ti on fi nfe ki o ri bee.

Ekini ni pe nitori oro iwe ipejo Ijoba Ipinle Ila Orun ko se alaye nipa ohun ti o fa pipejo na lese. Ekeji ni pe kootu giga ni Eko ko ni eto lati gbo ejo na.

Iketa ni pe ipejo na mu afojudi ati inunibini kan o fi abuku kan kootu giga lori pe ti kootu le ri pe o leto lati se ipa ejo ejo na.

Ni fifaramo oro atako yi, Agbejoro agba na se ibura bayi wipe Gegebi eje ketinleladota ninu iwe eto iseju fun Ijoba Apapo (Constitution) a se tubi alaye wa eyiti o fi nhan ni bi ile ejo kan ti ni eto lati gbo ejo-kejo ti nwon ba muwa siwaju re.

# Idasesile Miran Le Besile Ni Ibinni

BENIN CITY — Nitoripe won ko tete ri owo ise osu ti o koja gba, awon osise ile ise nibiti nwon ti nse roba ni ilu Ibinni ni Agbedemeji Ipinle Iwo-Orun (MIDWEST) se ipade kan ni lolo yi lati da sile ki osu yi to pari.

Okan ninu awon ti ngbe fun awon osise na so wi pe on ti kowe ebe si Ijoba Ipinle na lati san owo osu na lainiye igba, sugbon gegebi oro ti Ijoba ipinle agbedemeji so ri wipe ko ti si aye fun awon nisisiyi lati san owo osu na nitorije awon olopa nse iwadi lowo nipa oro owo kan ti nwon gbo wipe o sonu ni apo ijoba.

Eniti ngbe fun awon osise na tun nso siwaju ninu oro re pe, niwon bi o ti jepe kosi eyiti o kan awon osise ninu oro na, ko nidi fun Ijoba lati fi awon osise sinu inira bayi

Irohin na fi nhan wipe ni ojo kerindinlogbon osu to koja, awon olosa ja egbetala odin ogorun £2,500 lo lowo awon akowe ile ise na eyiti nwon fe fi san owo osu fun awon osise, ni kete ti nwon ti gba owo na tan ni banki, nigbati nwon npada bo wa si ile ise na ni ilu kan ti npe ni Ikpoba.

# Awon Olopa Owerri Gbogun Ti Awon Obinrin "Koforun"

OWERRI — O to gba ojole ti awon olopa Owerri ko wo ni owuro kutukutu ijeta nigbati nwon nwa awon obinrin 'koforun' ti nwon nfi awon olosa pamo si inu yara won kiri lati ko won kuro nibe.

A gbo wipe o to adorin awon obinrin koforun yi ti awon olopa na ri mu nigbati nwon bere wo awon ile-ero hoteli ti o wa ni arin ilu kiri, gbogbo won ni nwon si ko lo si esan awon olopa lati so lenu won.

Oga olopa kan ni iwa buruku ti awon olosa nfi oju awon ara ilu Owerri ari gbegbe re ni lojumo ni o jeki awon ma wa awon olosa na kiri lodo awon obinrin yi. Oga olopa yi ni o ni lati je wipe awon obinrin wonyi ni o nko awon olosa na pamo sile won.

Awon olopa yi si wa lenu nwon nso awon obinrin na lowo lese kiri.

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT ...



# Journey Across Africa

"We Africans do not need other people from outside to tell us about our customs and problem," This View, said Alvira Tanoh of Ghana in a BBC African Service broadcast, was shared by many Africans but not by her.

"I don't think there is anything wrong," she said, "if a stronger out of curiosity or interest writes about our customs, traditions and general condition in Africa. In fact, there is a great advantage and general conditions in Africa. In fact, there is a great advantage in seein your country and people through the eyes of another person. If he is impartial as Peter Lassen, the author of a book called "Young Africa', tries to be, you may learn a great deal. Moreover, Africa is so huge that someone living in one part cannot clain to know all that goes on in another part. It is through such books, therefore, that we get to know and perbapss understand our fellow Africans better and to appreciate the similarities and differences beween us."

Miss Tanoh said the Peter Lassen went to Africa to see how the Africa to tomorrow, which he believed would greatly affect the destiny of mankind, was shaping. In order to see things for himself, he drove across Africa, from Daka to Mombasa.

'He writes, said Miss Tanoh about most of the things we already know of about the peculiar and sometimes cruel customes about widespread superstition, and the poverty, disease and ignorance that is yet to overcome. But he writes with sympathy, and tries to see things from the African's points of view. Indeed, his simple straightforward sityl flashes of honour and sincesity and sympathy make his account less painful reading to any African with an open mind than most other books I have read."

He showed a keen appreciation of African virtues the friendliness and kinds the enjoyment and calm approach to life and the deep concern for fellow human beings as revealed by strong family ties and treatment of old people. He paid tribute the rapid developments now going on in agriculture, education industrialisation and medica care. The book also dealth with the problems raised by these changes and offered constructive suggestions for their solution.

The writer's own photographs said Miss Tanoh unlike the general narrative are a bit one-sided. They could have included some of the bridges schools universities hospitals and industrial establiments constructed by the new African governments Moreover too much space is given to the work of international organsations and not enough to what has been done by the people of Africa themselves".

However concluded Miss Tanor this book contained a great deal of useful information. Although it was meant for the British public, it was well worth reading by Africans

# New British Deputy High Commissioner In Nigeria

LONDON – The Secretary of Saate for Commonwealth Relations, Mr. Duncan Sandys, has approved the appointment of Mr. Edward N. Larmour to be British Deputy Hige Commissioner Nigeria, in succession to Mr. R. W. D. Fowler, C.M.G. Mr Fowler's appointment as British High Commissioner to the United Republic of Tanganyika and Zanzibar was recenrly annouced. Mr. Larmour is expected to take up his appointment in Lagos in September.

Mr Lamour, who is 47, was educated at the Royal Belfast Academical institatution, Triuity College, Dublin, and Sydney University, New South Wales. He saw war Service with the Royal Inniskilling Fusiliers and the Punjab Regimeut. In 1947 he entered the Burma before joining the Commonwelth Selations Office May 1948.

From 1641-1954, Mr. Larmour served on the staff of the British High Commissioner to New Zealand, and from 1954-57 was seconced to the Foreign Office for in Singapore, His prelent appointment, which he has held since 1661, is as Councellor on the staff of the British High Commissioner in Australia. Mr. Larmour is married and has one son and two dagguters.

## Inter-Secondry Schools Footba'l Competition Begins



LAGOS—Inter-Secondry School Zard Cup compitition began in Lagos last week, the compeitition is only for approved Schools in Lagos area and this year will be the last year for the Zard Cup

# Awọn Olopa Ni Oyinbo Kan Fe D'oju Ijọba Nigeria Bole

( O bẹrẹ loju kini )

ẹni ogeji ọdun jẹ olukọni ninu ẹkọ ṣunwona tabi itọju owo ninu iṣẹ-owo ṣe (Industrial Economics ) ni ile-iwe giga kan (University of Leeds) ni ilu Oyinbo o si ti desi ilu Naijiria ninu oṣu kẹrin ọdun yi fun iṣẹ wiwadi fun oṣu mefa rese lori bi nwọn ti iṣe 'Egbẹ Awọn oṣiṣẹ Ni Ilẹ Enia-dudu" ati lati le ṣe iwe lori rẹ.

Nigbati adajọ bi i lere lati ṣe alaye bi on ko ba ni wọ itimọ'e ọdaran na bẹ adajọ lati fọwọsi ki nwọn duro fun on ki on le raye ṣe eto ati gba agbẹjọro fun ara on. Lẹhinna ni adajọ tun bilere ibiti o ngbe, ṣugbọn o dahun pe on ki gbe ilu Naijiria ṣugbọn on ko le salọ.

Aṣ ti adajọ wa pa ni wipe nwọn igbati ẹṣẹ rẹ ti jẹ eyiti o nipọn pupọ gegebi alaye ti awọn olopa ṣe ati bi o ti jẹ pẹ iwadi si nọ lọ ọlọwọ lori ọrọ na o nfọwọsi pe ki nwọn lọ ti iọle.

Lẹhinna ni adajọ wa sọfun Victor pe o ni ẹtọ lati le fi ẹjọ kotẹmilọrun siwaju kotu giga lori ọrọ lori ọrọ didaro fun, o si paṣẹ fun awọn ọlọpa lati ṣe itanlowọ fun ọdaran na ni kikun ki o le ni anfani lati ṣe eto idabobo ara rẹ.

Ndi ọrọ yi awọn ọlọpa etelemuyẹn lọsi ile Alhaji H P Adebola ti o jẹ Balẹ egbẹ apapọjẹ apapọṣẹ ti awọn oṣiṣẹ ati alaga alaga fun Igbimọ ẹg'ẹ awọn oṣiṣẹ ni ilu Naijiria, nwọn si tu ile rẹ ka lati wadi ohun kan ti yio lodi tabi jẹmọ ọrọ yi fun wakati meji gbako.

Awọn ti nwọn ọ wadi bosa iwe abosi kan ... Alhaji Adebola Adele ọg-agba awọn ọlọpa kan ati ọlọpa meji ṣugbọn nwọn kori ohun kan ti olodi sofin.

Irohin kan ti a tun gbọ ... nipa ọrọ Oyinbo ... ti awọn Ọlọpa mu ... wipe awọn ikọ ile igbimọ aṣofin ilu

Gẹsi ti ni ki aṣoju awọn l'Eko gba lọya fun un, a tun gbọ wipe awọn akẹkọ Unifasiti Ibadan ti nda owo jọ lati gba lọya agbẹjọro kan fun Oyinbo na.

Nwọn ti tẹ waya idunnu si iyawo rẹ pẹlu awọn ọmọ rẹ wipe alafia ni o wa nibiti nwọn gbe fi pamọ si.

## Awọn Osise

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Gbogbo awọn oṣiṣẹ ile erọ gbohun - gbohun ni awọn ọga awọn ti kọwe si wipe dipo ọjọ kẹ indinlogbọn ti nwọn ma gbowo tẹ'ẹri, yio di ọjọ kẹta oṣu to mbọ ki nwọn to le gbowo oṣu yi.

Ki iwe owo awọn oṣiṣẹ ba le tete jale, aṣẹ ti de lati ọdọ ijọba fun akọwe ile-iṣẹ owo-apo ijọba ati ti ile asanwo oṣiṣẹ ijọba lati ma ṣe alekun wakati lori iṣẹ wọn, bakanna ni awọn akọwe ti nwọn wa nidi iwe owo oṣu awọn oṣiṣẹ ninu ile iṣẹ Reluwe, ile-iṣẹ eti ọsa ati tiile iṣẹ ona elẹtiriki ti gba aṣẹ lati ṣe alekun wakati lori iṣẹ wọn.

Awọn ile ijọba ti nwọn wa fun abojuto nipa isiro owo ni nwọn ti rọ awọn oṣiṣẹ wọn pata lati mura paraku si iṣẹ wọn ki owo oṣu le jalẹ ki ọjọ igbowo to de ni oṣu ti a fẹ bọ si.

## Awọn Ara Moka Dowolu Mosalasi Jimo Eko

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Alhaji Elias ṣe gba ilu awọn Larubawa lọ lati tọrọ owo lọwọ wọn.

Nwọn wa lẹnu irin ajo na nisisiyi ; a si gbọ wipe ọpọlọpọ awọn Olowo ilu Larubawa ni nwọn ti nlẹri wipe awọn yio fun wọn lowo gọbọyi ki wọn le ri mu lo fun Mọṣalasi Jimọ tuntun na.

THE ANSWER TO
TROPICAL CONDITIONS
★
UNMATCHED
AFTER SALES
SERVICE
★
MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ọ.a Ọṣatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos.